**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**
Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.
**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**TẸ̀SÍWÁJÚ NÍPA INÁ (2)**
**OṢÙ KẸJỌ, ỌDÚN 2023**
Ìwé Mímọ́ Kíkà: 2 Awọn Ọba 2
Ìjẹ́wọ́: Eksodù 14:15

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí ọgbọ́n àtòkèwá bàlé gbogbo àwọn tí O ti yàn láti ṣe àtìlẹyìn fún ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, fi ọ̀rọ̀ mi lémọlémọ sí ọkàn àwọn tí yóò rànmílọ́wọ́, kí ogun iyè ríra ẹ̀mí òkùnkùn má ba a jà wọ́n, ní orúkọ Jésù.
7. Mo kọ̀ láti tàṣé ayànmọ́ mi láyé, ní orúkọ Jésù.
8. Mo kọ̀ láti gba pàṣípàrọ̀ ìyówù sátánì fún ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
9. Mo kọ gbogbo 'èmi ni mo ni ọ́' sátánì fún ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ọ̀tá ìtẹ̀síwájú mi máa wọnú itìjú, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ọ̀rọ̀ òdì àti ìkéde lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi, di asán pátápátá, ní orúkọ Jésù.
12. Mo gbé ìdájọ́ kalẹ̀ lòdì sí gbogbo pẹpẹ búburú tí wọ́n gbé dìde lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
13. Mo kọ gbogbo ìṣàtúntò sátánì fún ìtẹ̀síwájú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
14. Mo yàlárọ gbogbo akó àdàlù bá ìtẹ̀síwájú, ní orúkọ Jésù.
15. Mo yọ orúkọ mi kúrò nínú ìwé àwọn afojú rí ìwé lásán láìjẹ́ nínú rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, jẹ́ kí ìkúkù tó n dí ìtànṣán ìtẹ̀síwájú ayé mi túká, ní orúkọ Jésù.
17. Mo kọ̀, mo fagilé àwọn orúkọ arẹ-ayànmọ́-sílẹ̀, mo sì sọ àwọn ràbọ̀ràbọ̀ wọ́n lórí ayànmọ́ mi di asán, ní orúkọ Jésù.

18.Mo kọ̀ láti ṣiṣẹ́ láìtójú ọ̀ṣùwọ̀n ìtẹ̀síwájú mi àtòkèwá, ní orúkọ Jésù.
19.Mo pàṣẹ kí gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi má a lọ, kí wọ́n má sì padà mọ́, ní orúkọ Jésù.
20.Olúwa, jẹ́ kí àwọn àyípadà ìyanu jẹ́ ìpín mi láti ọ̀sẹ̀ yìí lọ, ní orúkọ Jésù.
21.Mo kọ gbogbo ẹ̀mí ìrù ní gbogbo àgbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.
22.Ìdìtẹ̀lù òkùnkùn lòdì sí ìtẹ̀síwájú ayé mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
23.Bóyá sàtánì fẹ́ tàbí ó kọ̀, mo jí sínú ìlọsíwájú mi àtòkèwá nípa iná, ní orúkọ Jésù.
24.Iná ọ̀tá lòdì sí ìlọsíwájú ayé mi yóò tapadà, ní orúkọ Jésù.
25.Olúwa, jẹ́ kí pàṣípàrọ̀ ṣẹlẹ̀, bí ó bá jẹ́ èyí ni yóò jẹ́ kí n lọ síwájú, ní orúkọ Jésù.
26.Mo kọ ẹ̀mí ìrù, mo sì gba ẹ̀mí orí, ní orúkọ Jésù.
27.Gbogbo àkọsílẹ̀ ibi tí èṣù gbìn sínú ọkàn ẹnikẹ́ni lòdì sí ìlọsíwájú mi, túká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
28.Kò sí ohun ìjà tí wọ́n ṣe lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi láyé tí yóò ṣe nkan, ní orúkọ Jésù.
29.Mo kọ̀ kí àwọn ìkà ìdílé ṣàtúntò ayé mi, ní orúkọ Jésù.
30.Mo yàlárọ gbogbo ànfàní sátánì tó n gbógun lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi, ní orúkọ Jésù.
31.Olúwa, ṣínípọ̀, mú kúrò, kí O sì pàrọ̀ gbogbo ìránṣẹ́ ènìyàn tí ó ti takú láti dá ìlọsíwájú mi dúró láyé, ní orúkọ Jésù.
32.Olúwa, jẹ́ kí ọ̀nà mí tẹ́ dáradára lọ sí òkè nípa ọwọ́ iná, ní orúkọ Jésù.
33.Mo gba ìfòróróyàn láti tayọ ju àwọn ẹlẹ́gbẹ́ mi lọ, ní orúkọ Jésù.
34.Mo tú àwọn irinṣẹ́ ẹ̀mí tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi ká, ní orúkọ Jésù.
35.Mo gba àṣẹ lóri gbogbo àdúrà àjẹ́ tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìlọsíwájú mi, ní orúkọ Jésù.
36.Àgọ́ ara mi jẹ́ ẹyìn iná; adáhunṣe ìyówù tó bá fẹ́ fọwọ́kan ayé mi yóò jóná, ní orúkọ Jésù.
37.Olúwa, gbé mi lọ sínú dídi nlá gẹ́gẹ́ bí O ṣe ṣe fún Dáníẹ́lì ní ilẹ̀ Bábílónì, ní orúkọ Jésù.
38.Olúwa, rànmílọ́wọ́ láti dámọ̀, kí n sì gbógun ti àìlera-kí-àìlera tí ó lè dí ìtẹ̀síwájú mi lọ́wọ́, ní orúkọ Jésù.
39.Mo de gbogbo ọkùnrin alágbára tí wọ́n gbé kalẹ̀ láti dí ìtẹ̀síwájú mi lọ́wọ́, ní orúkọ Jésù.
40.Mo kọ̀, mo sì fagilé ìmọ̀ràn tó n rẹ ayànmọ́ sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.